**OJA ODUN**

Enyin Onigbeyawo ti Odun Keresimesi Oni-Ikomo, Oni-Isinku.

E wa ra oja wonyi ni edinwo fun Keresimesi :- nla Eyo, Dosini ati apoti Stout Wewe, Star Beer, Trikola, nla ati wewe Soda Water GordonGin nla ati Wewe, Aromatic Schnaps, nla ati Wewe, Martel Brandy, White Horse Whisky.

E ma wa fun oja yin lọdọ-

**O. A. Amoje & Bros.**
32, Bishop Street.
Phone 24310 Lagos.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Xmas Gifts**

**Victory Photos**
Offers You Bagains
FROM
Xmas to New Year
A week only. From
December 24 to January 1st 1958.

13, Ibadan Street East
Ebute Metta.

VOL. I No. 27, WEDNESDAY 1, JANUARY — JANUARY. 7, 1958 KỌBỌ KAN

# Ewon Osu Mesan Fun Fadina

**Eko**

Ogbeni Timothy Fadina, eniti o ti nfi igbakan je Olota ilu Otta ni awon Olopa ramu fun esun wipe, o se jibiti ni pa yiyi iwe oniwe pada.

Awọ enia meji ni ọrọ na bawi, ọkan ni Ọlọpa kan to nfi ọna han mọto ti orukọ rẹ njẹ Ogo, ekeji ni Timothy Fadina.

Ogo ti onṣe ọlọpa mọto sọ pe, ni asiko ti on mbẹ lẹnu iṣẹ ni on ri mọto kan ti o duro sibiti ko ni ẹtọ la ti duro si, on lọ ba awamọto na pe, ki o mu iwe ti o fi nwa mọto wa, ni Fadina ba mu iwe elomiran fun on, ni on ba ramu.

Adajọ Dadi Onyeama lo da ẹjọ na, o sọpe idi rẹ ti on ṣe ju Fadina si ẹwọn ni pe, o mọ pe iwe ti nwọn fi nwa mọto yẹn ko nse ti on ki oto lọ yi pada, nitorina ki o yara lọ si ẹwọn oṣu-mẹsan. Ṣugbọn Ọlọpa ti o nfọna han mọto ti o njẹ Ogo gan lo jẹbi ọrọ na nitorina lo se ni lati lọ si ẹ w ọ n.

## ITAN ILE IFE YIO BERE SI JADE NINU IWE YI LAIPE LAGBARA OLORUN

—

## SHOYINKA TUN GBE DE

Iwe Adura fun Arisiki lati Ilẹ Misirat 3/6d
Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Ẹsin Ojisẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan ati Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbeyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun ati Odu Ifa 12/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Turari Itaja 10/6d
Turari Ẹyọnu Ajẹ 10/6d
Abẹla Adura (Dragon Candle) fun Adura tete Dami lohun 15/-6d

Fi owo ransẹ si:-
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin.

## ORO AWON OLUWADI BEHIN YO

NIGBATI AWỌN OLUWADI ỌRỌ DE ILU EKO LATI ṢE IWADI KINI OHUN TI O JẸ IBẸRU FUN APAKAN TI KO PỌ LATI SORỌ JADE ?

AWỌN ẸGBẸ MẸTA LO YỌJU LATI SỌRỌ (1) LAGOS & COLONY STATE MOVEMENT. (2) UNITED MUSLIM PARTY (3) ABORIGINES OF LAGOS COLONY.

Ọrọ ti awọn ẹgbẹ mẹtẹta yi sọ niwaju Igbimọ Oluwadi nipe ko nṣe ilu Eko nikansoṣo ni awọn fẹ ki o wa gedegbe, ṣugbọn awọn nfẹ ki ilu Eko, Ikeja, Ẹpẹ, Ikorodu ati Badagry ki o wa pẹlu rẹ papọ, gẹgẹbi o ti wa ri, nigbati a npe e ni Lagos ati Colony State.

Alaga Igbimọ na Henry Willink dahun pe, awọn ti gbọ igilangọ ede lẹnu Oloye Davies ati Dingle Foot ti wọn jẹ alagbawi fun awọn apa kini bakanna ni nwọn si gbọ agbọye ọrọ lẹnu Oloye Williams ati Fani Kayọde fun awọn apakeji.

Awa si ti ṣe igbimọ larin ara wa lati daro bi o ba tọ fun wa lati ṣe bẹ, a si ripe ko si agbara fun wa lati ṣe ohun ti awọn ẹgbẹ mẹtẹta yi nfẹ fun wọn.

Nitoripe ni ọdun 1953 Ijọba Gẹsi pe gbogbo awọn Mujumuwa enia jọ, o si fi ọrọ na Isiwaju wọn bi tọ ki a pa ilu Eko pọ mọ agbegbe Iwọ Orun ilẹ Nijiria, tabi ki o wa gedegbe?

Lẹhin ti nwọn ti fi ọrọ we ọrọ tan, ni Sẹkituri agba ba paṣẹ wipe, ki ijọba ibilẹ ilu Eko wa gedegbe, ki a si ma pe e ni Federal.

Lẹhin ti Alaga na ti sọrọ pupọ oni. on ko le se ohun ti awọn enia na bere. Nigbayi ni ẹjọ di ẹjọ Oloko ẹṣin, ni nwọn gba ẹrẹkẹ ọtun ati ẹrẹkẹ osi, ni nwọn ba sọ ẹjọ di ẹjọ Awolọwọ.

## A NSE ORISIRISI EGBOGI

( LOKE PETESI YI )

**Fun Tita Ati Iwosan Arunkarun Ati Fun:—**

a Obirin to nwa oyun ( Iloyon )
b Obirin Alaboyun ( Titi yio fi bimọ )
c Obirin ti nkan oṣu se mọ lara
d Tọkunrin tobirin to nwa iṣẹ se, to nwa Ọkọ to nwa Aya
Ki Tọkunrin tobirin maṣe ri idaduro ibiṣẹ bi wọn tilẹ fun ni iwe idaduro
Itaja, Itaja, Itẹpọ-Tọkọ-Taya, Iṣọra, ati Ẹyọnu
g Imarale, Aleko, ( Adakọle ) ọkunrin.

Write:- J. B. Crownson-Odujọbi & Sons
*Top Floor*:- 16, Bamgbose Street, Lagos. Phone 24318

# IMOLE

ESIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA
*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

16, Bamgbose Street, Lagos.
Telephone: 21985

*London Office—*
*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN EKO—ṢILE MERIN KỌBỌ MERIN (4/4d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke-okun Ṣile mẹfa Kọbọ mefa 6/6d)


# E KU EWU ODUN TITUN

Enyin okawe Irohin Imọlẹ jake-jado agbaiye a ki yin lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati agbalagba wipe ẹ ku ewu ọdun titun ti a bọ si loni ki Oluwa alanu ninu anu rẹ jẹki a le fi inu didun la ọdun na jalẹ.

Awa ko le sọrọ lai ko bere lọwọ olukuluku wa loni ti ise ojọ kini ninu osu kini ọdun titun pe enyin ha ti kọ gbogbo iwa ibi ti ẹnikọkan wa ti hu silẹ ninu gbogbo ọdun ti a ṣe kọja yi? ẹnikẹni ti ko ba ti ṣe bẹ awa oniwe kegbe kikan fun oluwarẹ pe ki o pinu lati oni lọ lati bọra okunkun silẹ ki o si bọ sinu imọlẹ ki Oluwa gbọ adura wa jalẹ ọdun yi. Nitorina a bẹ gbogbo yin lati fi orin yi ṣe orin ọdun ki ẹ si kiyesi ọrọ orin na.

ORIN
TẠN 'MỌLẸ RẸ SI WA

| | |
|---|---|
| Tan 'mọlẹ Rẹ si wa | Jọ m'okan wa gbona, |
| Loni yi Oluwa, | K'ama wo oju Rẹ |
| Fi ara Rẹ han wa, | K' awọn 'mọde le kọ |
| N'nu ọrọ Mimọ Rẹ, | Iyanu ore Rẹ. |

Awa oniwe yi ki gbogbo ẹnyin oselu wa pe ẹ ku iṣẹ Oluwa ko ni jẹ ki ẹ ṣe ti, Oluwa yio ma fun yin ni ọgbọn kun ọgbọn yin, Oluwa ko ni kọdi aimọṣe si yin, ominira ti ẹ nsare rẹ yio ba wa layọ ati alafia ara. Ẹnyin ti ẹ nfori mu ti ẹ ko fẹ se ohunkohun a ke si yin, ọrọ ilu ki ṣe ti ẹnikan ti gbogbo-gbo ni, nitorina Iwe Irohin ni ede gesi ati ni ede Yoruba ṣe wa gbogbo rẹ si ni awọn oselu wa ma nyẹwo lojojumọ lati mọ ẹdun olukuluku nitorina ti ẹnikẹni ba ri ohun ti o le ran ilu lọwọ o le kọ ẹdun ọkan rẹ ni sinu iwe Irohin ti Ijọba ba si ri, wọn ni lati gbe ọrọ na yẹwo.

Bakana ni a tun kesi ẹnyin ole agbe wiri pe ki ẹ bọra okun silẹ ẹ bọ sinu imọlẹ ninu ọdun titun yi ki ki imọlẹ le ba yin, ko si ẹniti o le sisẹ ninu okunkun ti ilọsiwaju yio ba ohun ti o ba nṣe nitorina ẹ pinu lati oni lọ lati ṣe isẹ rere. Ẹnyin ti ẹ ni fi ẹnu ba ọmọnikeji yin jẹ ti omiran ti lọ si ọgba ewọn isẹ okunkun ma ni eyi, nitorina a bẹ yin ẹ bọra okunkun silẹ ki ẹ si bọ sinu Imọlẹ.

Lakotan ara a ki gbogbo ẹnyin ti idanwọ buburu ba ninu ọdun ti o kọja lọ yi, Ọluwa yio dun yin ninu, ninu ọdun titun yi, Ẹnyin onisowo ti ẹ ko ba ode pade ninu ọdun tokọja yi Oluwa ninu anu rẹ yio jẹ ki ẹ ri Ere ko lọdun titun yi ẹ o bode pade, ẹnyin ti ẹ bi abiku lọdun tokọja, Oluwa yio jẹ ki ẹ bi abiye. Gbogbo ẹnyin aboyun ẹ o ru re ẹ o si sọ re a o gbohun Iya, ati ọmọ. Oluwa koni fi ọlọjọ ranti olukuluku. Oluwa ko gbe Ire ko gbogbo wa lọdun yi.

# Iwe Si Olotu

## IRANTI FUN MUSULUMI ORO

Olotu,

Inu mi yio dun bi Olotu bale gbami laye lati dupẹ lọwọ eni Ọlọrun wa Alufa Ọlọrunkẹmi Ogbomọshọ. fun iranti ti o ṣe fun awa Musulumi Oro nipa ọrọ Mọsalasi Jimọh ti o pin si kelekele ninu iwe IMỌLẸ ti 30/10/57. Mo dupẹ pupọ loruko mi, ati ti ọmọ Oro to wa ni Ilu Eko ati nibikibi ni ilẹ Naijiria fun iranti ti ẹru Ọlọrun yi ṣe wa nipa ede-aiyede yi, Oluwa yio san ẹsan olore fun Ọgbẹni yi Amin.

Ni afikun ọrọ Alufa yi gẹgẹ bi ọmọ Oro mo fẹ tun ṣe ẹyin ara Oro ni iranti pe o jẹ ohun abuku pupọ ki a sọ pe awa Imale ti a pe ara wa ni Ọmọ Iya kanna ko gbọ ohun ara wa, mo si fẹ ki olukuluku wa mọpe gbogbo ohun ti a ba ṣe ni ile aiye yi, aiye ni yio gbesi, ṣugbọn ohun ti a ba ṣe fun ti Ọrun ni ao ba niwaju ni ọjọ ti a ba fi ilẹ bora bi aṣọ, nipa idi eyi ko ba dara bi aba le pa ọrọ aiye ti ki a ṣe ti Ọrun.

Mo pe gbogbo ẹnyin alagba Imale Ẹku mẹsẹsan Oro ati ẹnyin Alufa ọmọ Oro to wa ni ilu Eko ki e dori kodo si ọrọ Alufa Ogbomoshọ yi, ki ẹ ṣe eto ki ẹ pa Mọsalasi Jimọh pọ. Mo tun pe ẹnyin Olowo ati gbajumọ Imale Ẹku mẹsan Oro pe eleyi ni asiko tiyin o si yẹ ki ẹ lo asiko na fun iranti titi lai, ẹyin ni ẹnu yin to ọrọ ti ẹsi le sọ, o yẹ ki ẹ ṣe agbara ki ẹsin Ọlọrun ti o fi ran Anabi Muhammed Ojiṣẹ rẹ maṣẹ bajẹ lasiko tiyin. Mo si tun fẹ ki ẹ ṣe iranti pe kosi ẹniti yio ṣe ti Ọlọrun ti Ọlọrun koni ṣe tirẹ.

Lẹhin eyi mo tun pe ẹyin ọdọmọde Imale Ẹku mẹsẹsan Oro ki onikaluku ba awọn alagba wọn sọrọ ki ẹsin Oluwa maṣe bajẹ loju aye tiwa gẹgẹ bi koṣe bajẹ lasiko ti awọn baba to bi wa.

Bi ẹyin ọmọde ba ba awọn alagba sọ tan ki esi tun pe ara yin jọ ki ẹ ṣe imọran bi gbogbo ọrọ yi yio ṣe to. Oluwa yio si fun yin ni ọrọ na ṣe (Amin.) Eyi ni imọran mi siyin

Emi ni tiyin ninu Islam
Alufa Atunkanṣe
ỌMỌ ORO

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati ba awọn okawe ẹgbẹ mi lọkunrin, lobinrin, lagba ati ọmọde sọrọ ninu iwe yin ti o kun fun ẹkọ ninu ọdun ti a wọ yi.

Mo ki yin ẹnyin okawe ẹgbẹ mi ti ẹ nkawe Imọlẹ, oju ko ni tiyin, o ti pẹ ti mo ti nkawe Irohin ṣugbọn nigbati mo ti nkawe Imọlẹ mo ri oye pupọ ninu rẹ pẹlu ẹwẹ orukọ Iwe na tilẹ fa enia mọra pupọju nitoripe gbogbo wa lo mọ wipe ko si ẹniti yio gbadura wipe ki oun ki o wa lokunkun biko ṣe Imọlẹ nitorina mo ki yin daradara.

Mo si fi iwe mi yi pe ẹ ku ajọyọ ọdun titun ti a bọ si yi, Oluwa ko jẹ ki a fi inu didun gbe ọdun dopin a ko ni ṣẹku, Oluwa ko jẹki a gbẹhin awọn arugbo wa, gbogbo awọn Akẹkọ lọkunrin ati lobinrin ti wọn wa nilu Oyinbo Oluwa ki o fi ẹkọ wọn ye wọn ki o sọ wọn bọ pẹlu ayọ ati alafia, awọn ti wọn si nmura lati lọ ninu ọdun titun Oluwa yio pelu olukuluku lọna irin ajo rẹ awa ti a si wa nihin Oluwa ko ni jẹki a ri asure pe oju ko ni ti gbogbo wa o.

Olotu mo dupẹ pupọ lọwọ rẹ fun aye ti o gba mi oju ko ni ti ọ, Iwaju ni iṣẹ yin yio ma lọ, ẹnyin yio si ma ri iyọnu ọmọ araiye.

Emi ni
JANET OGUN
IFỌ.


WANTED

2 Apprentice Printers

APPLY

Modupe Printing Press

16, Bamgbose Street,
LAGOS.

## PUBLIC HOLIDAYS

New Year's Day ... Jan. 1
Good Friday ... April 4
Easter Monday ... April 7
Lailatul Quadri ... April 15
Ramadan Day ... March 21
White Monday ... May 25
Eid-El-Karbir-Fes June 27
Miharram Hijuruyyah July 17
Back Holiday ... August 4
Lailatul Ashura Night July 24
Birthday Mohammed Sept. 24
Christmas Day ... Dec. 25
Boxing Day ... Dec. 26

## Phases of the Moon

Full Moon.... January 5
Full Moon....February 4
Full Moon.. ...March 5
Full Moon... April 4
Full Moon... May 3
Full Moon ... June 1
Full Moon.... July 1
Full Moon.... August 7
Full Moon ... September 6
Full Moon ... October 6
Full Moon ... November 4
Full Moon ... December 4



ALHADJI TAFAWA BALEWA
Olotu Apapọ Ilẹ Naijiria



ỌGBẸNI E. A. ADENIJI
OLOTU IWE "IROHIN IMỌLẸ"

## 1958 Calendar 1958

**January**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | 1 | 2 | 3 | 4 |
| 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 |
| 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 |
| 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 |
| 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | 31 | |

**February**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | | 1 |
| 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 |
| 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 |
| 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 |
| 23 | 24 | 25 | 26 | 27 | 28 | |

**March**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | | 1 |
| 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 |
| 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 |
| 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 |
| 23/30 | 24/31 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 |

**April**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
| 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 |
| 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 |
| 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 |
| 27 | 28 | 29 | 30 | 30 | 31 | |

**May**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | 1 | 2 | 3 |
| 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 |
| 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 |
| 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 |
| 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | 31 |

**June**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 |
| 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 |
| 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 |
| 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 | 28 |
| 29 | 30 | | | | | |

## 1958 Calendar 1958

**July**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
| 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 |
| 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 |
| 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 |
| 27 | 28 | 29 | 30 | 31 | | |

**August**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| 31 | | | | | 1 | 2 |
| 3 | 4 | 5 | | 7 | 8 | 9 |
| 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 |
| 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 |
| 24 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 |

**September**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 |
| 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 |
| 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 |
| 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 |
| 28 | 29 | 30 | | | | |

**October**

| Su | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | 1 | 2 | 3 | 4 |
| 5 | 6 | 8 | 7 | 9 | 10 | 11 |
| 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 |
| 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 |
| 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | 31 | |

**November**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| 30 | | | | | | 1 |
| 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 |
| 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 |
| 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 |
| 23 | 24 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 |

**December**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 |
| 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 |
| 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 |
| 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 |
| 28 | 29 | 30 | 31 | | | |

## Ẹ KU IYEDUN O

Inu wa dun lọpọlọpọ lati kọwe si yin li akoko ibẹrẹ ọdun titun yi, ki Oluwa jẹ ki a ṣe ọpọ rẹ li ayọ ati alafia ara; gbogbo ibanujẹ ọdun 1957, Oluwa ko sọ di ọpọlọpọ ayọ ati ẹrin fun gbogbo wa jakejado. A ki yin, ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun. Oluwa ko ṣe ọdun yi labo fun wa. Amin.

Inu wá dun lati sọ fun yin wipe loni ti iṣe ọjọ kini oṣu kini ọdun yi ni iwe wa Irohin Imọlẹ di ọmọ oṣu mẹfa. Nitorina a dupẹ pupọ lọwọ gbogbo ẹyin ọkawe wa ti ẹ ko binu wipe iwe wa na kere, ti ẹ si nü ifẹ ati ayọ ra; nitoripe nigbati a bẹrẹ iwe na ni oṣu kẹfa sẹhin, a ko mọ pe ohun ti yio gba iyi ni, ṣugbọn nisisiyi, iwe wa na ti gbayi, gbẹyẹ, o si ti gbajumọ kakiri gbogbo ilẹ karọ-o-ji-re o ti di ọka ati ẹran. A dupẹ pupọ.

Olotu

Printed and Published by Modupe Printing Press, 16. BamgboṣeSt, Lagos Phone: 21985.
Olotu E. A. Adeniji 4 Ibadan Street East Ebute- M